Bibeli fun awon omode

# Irin ajo iyanu Poolu



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Poolu ati Sila, iranse
Jesu, wa ninu tubu.
Rara, won ko se ohun
to buru - won ti le emi
aimo jade lara obinrin
kan.  Won fi orisa han -
won n sin eniyan, ti o n gbe
ni Fillipi agbara Olorun otito
ati omo
Re Jesu.
Fun Idi
eyi won
mu won,
won na won si
ti won mole.



Iwo o ti ma ro pe Poolu ati Sila yoo binu ati banuje. Sugbon won ko se bee. Ni pato, loganjo oru, won dide duro won n korin iyin si Olorun, Gbogbo awon ara tubu sin teti si won.



Lojiji, orin dake, Olorun ran ile riri lati mi tubu. Gbogbo ilekun si si sile. Gbogbo ide won si ja.





Oh! oh! Onitubu se bi awon ara tubu ti sa lo ni. Bi enikan ba salo, a o pa oluso tubu ni, Ni ibanuje, onitubu fa ida re yo, o fe pa ara re.

Sugbon Poolu ke kara “Ma se pa ara re, nitori gbogbo wa wa nihinyii”. Nigbati onitubu ri eyi, o wi pe, “Alagba, kinni ki n se kin le la?” Won wi pe “Gba Jesu Kristi Oluwa gbo a o si gba o la, iwo ati awon ara ile re” pelu ayo, onitubu naa si gbagbo.





Won tu won sile ni ojo keji, Poolu on Sila gba awon ilu miiran lo, won soro Jesu fun awon eniyan. Awon miiran gbagbo, awon kan n gbero ati pawon lara. Sugbon Olorun wa pelu awon iranse pe. Ni oru ojo kan, Poolu waasu fun wakati pupo. Arakunrin kan joko nibi ferese to si sile o ti sun lo, se o le so ohun ti o sele.



Gbogbo eniyan mo pe arakunrin naa ti ku. Sugbon Poolu sokale o si gbe O wi pe, “Iye mbe ninu re.” Won mu arakunrin naa wa laaye, inu won si dun gidigidi.

Poolu ati Sila ni ilakoja to po bi won rin irin ajo lo si Eiropu. Okan ninu ilakoja sele nigba ti won wa ninu oko oju omi. Ko si idakoro mo; sugbon asia oko oju omi, tete so soke laarin iji.





Poolu wa ninu oko oju omi, nitori won ti mu u. Ni bayi o ni la ti farahan niwaju Oloye n Romu, olu ilu agbaye. Afefe lile ti da oko oju omi duro. O dabi pe iji lile wa ni iwaju. Irin ajo nan ko dan mooran fun Poolu ati awon ara tubu, gege bee ni fun atuko.

"Ara, Mo n wo ye pe irin ajo yii yoo yori si ibi" Poolu kilo, Balogun naa ko teti sile.  Won nlo ninu okun.  Nigba ti iji nla kolu won, won so okun yika oko naa nireti pe ko nii ja si meji.  Bi oko oju omi naa ba fo, ibi omi ni won o sin gbogbo won si.



Oko naa n ri debi pe Balogun be gbogbo eniyan lati mu fuye. Ni ojo keta, won si wa oko naa gun le. Boya iyen le ran won lowo.



Nigba ti o di oru Angeli kan duro legbe e Poolu o si wi fun un pe ohun kan yio sise bo ti ye.  Awon yooku nan gba imulokan le nigba ti Poolu wi pe “Mu okan le ara; nitori mo gba Olorun gbo pe yio se bi o ti so fun mi.  Sibe, a gbodo sa lo si erekusu.”



Leyin ojo die, oko naa ba le si egbe erekusu Melita. O ja lu ori apata, o si fonka. Balogun naa pase fun eni ti o le wemi lati bo si ori ile ni kia kia, Awon yooku jade lai farapa ati awon miiran lori oko ti o fo.



Ni Melita, Olorun jeri agbara Re. Nigba ti won sa igi jo lati dana. Paramole bu Poolu san. Awon eniyan lero pe yooku. Sugbon paramole naa ko paa lara. Nigba naa ni won wi pe orisa ni Poolu. Awon alaisan wa, Olorun si mu won larada. Leyin igba ti Poolu gbadura fun won.



Paripari, Poolu gunle si Romu. O gbaa to odun meji ki a too gbo oro ejo re. Ni akoko naa, Poolu ya ile gbe o si gba alejo. Nje o mo ohun ti Poolu nba awon alejo re so? Ijoba Olorun! Jesu Kristi Oluwa! Poolu je iranse Olorun ni Romu, ati gbogbo irin ajo re.



“Emi ti ja ija rere, Emi ti pari ere ije, Mo ti pa igbagbo mo”, Poolu kowe lati Romu.  Bibeli ko so fun wa bi igbeyin re ti ri, sugbon akosile so pe age ori Poolu ni Romu nipa ase oloye Nero.  Poolu ku gege bi o ti gbe - iranse Olorun olotito to n so oro nipa Jesu fun awon elomiran.



Irin ajo iyanu Poolu

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ise Awon Aposteli ori Kerindinlogun, ori ketadinlogbon, ori kejidin logbon

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.